ELETI ỌFE

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJO'

VOL XIV NO 930 LAGOS SATURDAY JULY 18—JULY 24 1964 KỌBỌ MEJI (2D)

AWON OSHUGBO GBODE

# Awon Musulumi Eko Ko Oku Oba Adele

EKO—Rogbodiyan tani yio sin oku Ọba Adeniji Adele Keji ti o waja lati ijẹfa ti awọn musulumi Eko pẹlu awọn ẹgbẹ Oshugbo ti nfa mọ ara wọn lọwọ ti fi ori ti si ibi kan ni owurọ ana nigbati awọn alawo oshuggo gbe ilu gbẹdu jade si agbala Ọba lati ṣe ikede fun awọn ara Eko wipe awọn ni awọn yio sin Ọba na lọla, awọn Imale ni awọn ko ni fọwọ kan oku na lati sin rara.

A gbọ wipe Apena awọn alawo Oshugbo, Oloye Ogundare Awiṣẹ ti ranṣẹ si gbogbo awọn Oloye Onifila funfun Eko wipe bi nwọn ti nsinku Ọba na, gbogbo wọn si fowọ si i. Lẹhin eyi o ni ki awọn Imale Eko jẹki awọn mọ bi awọn na ba ti fẹ sinku na si.

Gbara ti awọn Imale ti gbọ iṣẹ yi ni gbogbo awọn lemọmu patapata tiṣe ipape, nwọn si fohnn sọkan wipe awọn ko ni kirun si oku na lara rara.

Nwọn ni nkan ti ko ni jẹki awọn ba wọn sinku na pọ, nwọn ni oku imale o gbọdọ di ọjọ kẹta nile, afi ti o ba ku sile iwosan, ti nwọn ko tete gbe oku na fun wọn. Nwọn ni oku Ọba Adele ti di oku ti anko okuta-yinyin bo bi ẹ a tutu, eyi ko si tọ suna rara.

Ọkan ninu awọn ogunnagbongbo alawo Oshugbo, Oloye O.A. Fagbenro Beyioku ni on kansara si Lemọmu-agba awọn Musulumi Eko fun ipinnu wọn na: o ni ilu ki wa ko mọ ni oro-ile rẹ pẹlu nkan abalaiye awọn ara ilu. O ni gbogbo ara Eko ni ọrọ awọn imale jọ lojú pupọ.

A gbọ wipe gbogbo awọn Oloyemarun ti nwọn wa ninu ija pẹlu Ọba Adele ki o to ku ni nwọn a pesẹ nibi isinku na ni iga Idunganran.



Ologbe Ọba Adeniji Adele II

A ki gbogbo awọn Ẹbi Ọmọloku pe wọn ku aṣẹhinde, Ọlọrun ko tẹ wọn si afẹfẹ rere.

## Awon Ara Eko Si Oja Ebute-Ero Tuntuu

EKO — Ni ọjọ Ru ti o jẹ ọjọ kẹdogun oṣu yi ni Alhaji Musa Yar'Adua, Minista fun eto Alafia ilu Ekoaṣeyẹ ṣiṣi ọja Ebute Ero ti nwọn fi ọkẹ mẹwa pọun (£200,000) kọ ni ilu Eko pẹlu ogunlọgọ awọn enia ti nwọn wa sibi ẹyẹ na, kiki awọn ti nwọn jẹ obinrin Ọlọja.

Awọn obinrin Ọlọja bi ẹgbẹgbẹrun wọn ni nwọn kọkọ fi ere ilu ati ijo bẹrẹ ariya ṣiṣi ọja na, pẹlu ariya ati ọnini ẹgbẹ wọn lọwọ ati aṣọ ape to gbamuṣe lara wọn, nwọn nkọrin orişirişi eyiti nwọn fi yin Oloye Awolọwọ, Olori ẹgbẹ Afẹnifẹre (A.G) lọjọ na.

Ẹgbẹrun isọ l'o wa ninu ọja na o si tobipupọ. Ninu ọrọ ti Minista na sọ lati şi ọja na, o sọ fun awọn enia pe, kikọ ọ a titun yi dipo eyiti o ti wa nibẹ tẹlẹ ri ti o jẹ ohun ailera fun gbogbo enia, jẹ ọkan ninu awọn eto pupọ to wa nilẹ eyiti Ijọba Apapọ pẹlu iranlọwọ igbimọ Kansulu Eko pinnu lati ṣe fun awọn ara ilu Eko, atipe on şakiyesi ilọsiwaju ti o ngbilẹ lojojumọ larin ilu Eko, lori awọn iṣẹ owo şiṣe ti kansulu Eko nṣe.

O tun sọ pe aṣa lati ma ta ki a situn ma ra jẹnkan to ti ṣẹ ti pẹ bi igbati enia ti wa lori ilẹ tipẹ ba anna. Lẹhinna ni Iyafin Mọdinọtu Alaga, ti o jẹ Iya Ẹgbẹ awọn obinrin ọlọja wa fi aṣọ oke meji ta Ọgbẹni S. Mayaki lọrẹ, ẹniti o jẹ akọwe ilu ni ile iṣẹ L.C.C. ati Ọgbẹni Adeniji Coker ti o jẹ Akapo ile iṣẹ kanna.

Iyafin Mọdinatu tun du pẹ lọwọ awọn alaṣẹ Lagos City Council fun mimu ileri wọn ṣẹ nipa si ọ ọja na, o si bẹ wọn lati mọ dau pe ọja Ebute Ero lo jẹ gbakan-o-ṣubu ti o si fa ogunlọgọ awọn onişowo mọra lati Oke-Okun ati igboro Ilu wa lati wa ba awọn obinrin ọlọja ṣowo.

O tun rọ wọn pupọ lati ma fi iwa pẹlẹ ba awọn lo, ti nwọn ba si nilẹ ki awọn ṣe imọtoto ibikan larin Ọja ki nwọn sọfun awọn pẹlu ohun irẹlẹ, lọgan şiṣe ni yio jẹ fun awọn.

# Awon Olopa Ni Oyinbo Onirungbon Ba Awon Osise Gbimo Ote

IKEJA—Awon olopa ti mba Dokita Allen, Oyinbo onigbon kan lati ilu Geesi sejo lori idite po lati do u ijoba Apapoşe ti ilę Naijiria bolę sofun ada o kotu kekere ti o ngbo ejo na ni Ikeja wipe Dokita Allen ati awon meta miran fi ara won se okanşoşo lati da ęgbę oşelu kun silę ti nwon fę pe ni Ęgbę Oludande ti yio gba awon ara ilu Nigeria lowo ajaga awon Olowo yato si Ijoba ti o nse akoso nisisiyi.

Oro yi ni awon olopa sofun adajo nigbati adajo na beresi gbo ti awon olopa ko pelu Allen ni Kotu Ikeja ninu ose yi: osu meta ti nwon mu won fun ni wipe wipe nwon didite po, lati doju Ijoba bolę ekeji fun şişe apamopamo po tite iwe oro afojudi ati abuku Ijoba oruko awon merin ti nwon mu pelu Dokita Allen ni Sidi Khayam, (omo ęgbę asiwaju awon oşişę) Oluşegun Adebayo ti o nşe işę (Olu oni) ati Jonas Abam okan ninu omo ęgbę aşiwaju awon oşişę miran).

Ohun ti awon olopa un fi se isongbe esun wonyi ni awon iwe kan ti nwon ri ninu ile Adebayo nigbati nwon nse iwadi ejo na lowo, dię ninu awon iwe na ni nwon fi edu ikowe (pencil) ko, omiran pelu tada (ink nwon si tun se ki o oro inu won ni ilai oyanju tabi ede ena.

Nigbati nwon beresi gbo ejo na Ogbeni Cecil H. Miller, eniti o je adele Olutonisona lori esun awon odaran fun Ijoba Apapo sofun adajo pe awon esun wonyi ko kan awon Asiwaju ęgbę awon oşişę rara; awon bi Ogbeni M. A. Imodu, Alhaji H.P. Adebola ati awon miran pelu, Ti ose awon ti awon ko wa si iwaju adajo yi lo ime lati da ina otę na silę pelu awon miran. Ogbeni Cecil Miller ni nwon gbe ejo yi siwaju fun gbigbo ni pataki fun idabobo ijoba ati awon enia ti nwon wa ni işędalę labę ofin.

Ninu oro ti Dokita Allen so ninu iwe kan ti awon olopa ri ko, o ni on olukoni giga fun opo awon omo ilę Nigeria ti nkęko nipa işę aşiwaju fun ęgbę awon oşişę ni ilu Oyinbo ninu ile eko giga Leeds University, on si ti fi igba kan şe adajo tęlęri ni ilu Oyinbo, beni on si ti wa si ilę enia dudu lati şe aşoju eto ofin nipa ilu şişe lati iwe ori won.

Gegebi oro kan ti nwon ko sinu iwe kan ti awon olopa ri ko ninu ile Allen, nwon se apejuwe Ogbeni Imodu bi akoni ati ogboiya enia kan ti o nşe agbaso fun gbogbo ęgbę awon oşişę ni ilu wa yi, a si tun gbo pe Ogbeni [illegible] an Dokita Oni ko iwe kan ti nwon ka si eti kotu ninu eyiti o so o ye ki awon aşiwaju fun awon oşişę ma a şe ipade nigba-ugba ki nwon ba le wa ni ifowosowopo nitoripe a'ko o ija gan ni awon pelu awon amunisin ti won nşe alamojuto Ijoba Ijoba Nigeria.

Nwon koi ti pari riro ęjo na.

---

# Egbe Oduduwa Yan Oloye

MUSHIN — Awon egbe omo Oduduwa ti eka Odi-Olowo ni Mushin şe ipade nla kan ni ojo kerindilogun oşu kefa odun yi ni No. 2 Opopo Kole ni Odi Olowo lati yan awon oloye ti yio ma to ęsę ęgbę na.

Opolopo enia ti nwon je omo egbe ni nwon wa sibi ipade na ti gbogbo ile kun şibaşiba:

Awon ti nwon yan gegebi oloye egbe na ni Ogbeni A.A Adepitan Babi - ęgbę M. Onipede, Alaga egbe E Egunjobi Akowe ęgbę, M. Kafari Akapo, M A. Cole, P. Fasanya, otun Balogun Y. Sule Are Oduduwa B.A Martins, Alabojuto eto owo, J S Odetola Bisobu Hanson ati L Olateju gegebi Baba Isalę Iyaafin M A Onisemo, Iya Egbe ati Iyaafin Omowunmi Otun Iya Egbe.

---

# Egbe Irawo Owuro Ti Ijo Serafu Se Ajodun Ni Iwaya

IWAYA — Ni ojo Abameta ti nşe ojo kerin osu yi ni awon omo ęgbę Irawo Owuro ti Ijo Sosi Kerubu ati Serafu şe ajodun oloyinmomo kan ni ilu Iwaya Yaba eyiti o şe iyato lati igbati nwon ti nşe ajodun bę opo awon ęgbę Serafu lati igboro ilu Eko titi lo de Agege ati awon ti nwon peli udun ati ęyę si ajodun na.

Awon ti nwon je opomulero ninu Ijo na ni awon alagba Ogbeni S M Ajose Ojişę Olorun agba Ijo ati Igbakeji rę, Ogbeni Agbelekale, ninu ajodun na ni nwon yan awon Oloye ęgbę ti yio ma şe akoso eto ęgbę.

Awon na ni Ojişę Olorun Ogbeni M A Robert, Babasalę, Iyaafin Lea Abikoye Iyasalę Ogbeni J A Matanmi Alaga ęgbę, Iyaafin O Olatunji Alaga Obinrin Ogbeni M A Olatunji Aşiwaju R.B Ajayi Akowe ęgbę O Ajose Akowe olupolowo ęgbę J.F Onibudo Olubojuto eto owo Iyafin B A Tytler Akowe obinrin ati Ogbeni S Martins Akapo ęgbę.

---

# Awon Odo Egbe Demo Se Ipade lEko

EKO—Ni ojo Eti ti nşe ojo kęwa oşu yi ni Oloye Fagbenro Beyioku aşiwaju ęgbę Dęmo ni ilu Eko şe ipade nla kan ninu ile sinima Rialto ni Offin pęlu awon odo omo ęgbę Dęmo fun ifidlelę ęka ti awon ęgbę odo ipade na si je eyiti o larinrin pupo.

Oloye Beyioku ni o kọkọ soro lati şi ipade na oro ti o so si kun fun ogbon ati oye, o tun şe alaye lori idi re ti awon fi da ęgbę odo silę ki gbogbo enia le ni oye nipa eyi, o fi itan kekere kan gbe oro rę lęsę.

Lęhinna ni eniti o je alaga fun ęgbę wa yi ni Ward A 4 ni ilu Eko ogbę ni Taju Thompson soro iwuri o si so ninu oro rę pe on ki gbogbo awon odo ęgbę Dęmo pata pe nwon ku orire o si tun tę mo won leti pe ki nwon gbidanwo lati şişe tokantokan fun ilosiwaju ilę baba won.

O tun sofun won wipe gęgębi baba ati iya awon odo nilati ko nipa oye ti enia ima i o lati ma fi to awon ęlomiran sona ti o to, lęhin eleyi o şe adura Ki o to pari oro rę o şe ileri fun awon odo na pe on yio ran won lowo lowo lonakona fun ilosiwaju ęgbę won yi ti on ba ri gęgębi nwon ba ti şişę si.

Eniti o tun soro ni ogbę ni T O S Oniyide, ti o şe adura fun awon omo ęgbę na fun ęmi işokan idagbasoke nini gbogbo alubarika titi lai. Lęhinna o şe alaye idi rę ti on fi kęhin si ęgbę Alakuko ti on si tun wa di omo ęgbę Dęmo.

Gbogbo awon ti nwon sibi ipade na eyiti o tun papo mo iranti ojo ibi Oloye S. L Akintola Olotu Iplulę Iwo Orun je ojile lęgbęta enia o le meji ati ya ojo na si mi ari gindin pupo.

Awon enia pataki ti nwon wa sibi ipade ni Alhaji Mogaji Iyaafin J. Thompson Iyaafin Bamgbade Madojutimi Akerele ati Sinatu Alaga Oja Ebute Ero ati opolopo awon omo ęgbę.

# Tani Fe Pa Oloye Awolowo Lewon ?

IBADAN — A gbọ irohin kan wipe awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ (A G) ti kọwe ni ẹmeji si Ọlọla Tafawa Balewa Olotu Ijọba Apapọṣe ati Ọlọla Nnamidi Azikiwe Gomina agba nipa ọrọ ti awọn gbọ wipe awọn enia ngba imọran lati wa pa Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ, aṣiwaju awọn ọmọ ẹgbẹ Ọlọpẹ ninu ọgba ti o wa.

A gbọ wipe ninu ipade abẹ ile kan ti awọn ogunnagbongbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ṣe ninu ọsẹ ti o kọja ninu ile ẹgbẹ wọn ni Oke-Ado ni Ibadan, gbogbo wọn ni nwọn fẹnu sọkan wipe awọn fun A l h a j i Adegbenro laṣẹ ki o tun kọ iwe miran dipo eyiti nwọn ko si Ọlọla Tafawa Balewa ti nwọn ko ti gbọ esi rẹ si awọn alakoso Ijọba na.



**Alhaji D.S. Adegbenro**
IGBAKEJI AṢIWAJU ẸGBẸ AFẸNIFẸRE

Gẹgẹbi irohin ti o ta si wa leti nipa nkan ti nwọn kọ sinu iwe wọn na ti nwọn fi ninu rẹ ranṣẹ si awọu Ọga ile ẹwọn, nwọn ni awọn gbọ wipe awọn ọta Oloye Awolọwọ kan ngbero lati fi majele sinu onjẹ rẹ l'ọgba ẹwọn ninu wipe nwọn ngbe e lati ọbga ẹwọn kan de ọgba ẹwọn miran, ki nwọn ba le pa a.

A gbọ wipe ninu ẹda iwe kan ti nwọn kọ na, nwọn fi kan sọwọ si Olori awọn dẹrẹba ẹlẹwọn wọn, Oloye Giwa Osage.

## E Ka oro osise Ni Enugu

(Loju ewe kefa)

# AkoweKan Gb'emi Ara Re

APAPA Ọgbẹni akọwe kan ẹni ọdun mẹrindinladọta ti oruko rẹ njẹ Sule Abioye ti o ṣiṣẹ ni ọfisi asanwo ti awọn ṣọja ni apapa ni a gbọ pe o ku ni ọjọ Iṣegun (Tuesday) ti nṣe ọjọ kẹtalelogun oṣu yi fun oro ọgbẹ ti o ṣa ara rẹ.

Sule Abioye fi ọbẹ la ọfun ati ikun ara rẹ ninu ile ibiti o ngbe ni NO 20, Opopo Ogunmokun (Ogunmokun Street) ni Mushin, ati pe ni iele ti akan yi nṣẹlẹ ni awọn ọ ọpa ba gbe oku rẹ ọsi ile lakulaku ti Ikẹji fun ayẹwo.

Irohin ti a gbọ nipa nkan to le fa iku Abioye ni wipe o n a t i ẹnikan nṣe ẹjọ lori ilẹ kan laipẹ yi ṣugbọn awọn ọ ọpa ko ti dariko oluwarẹ. Ọgbẹni Abioye fi ọmọ rẹ obinrin kan ṣoṣo ọmọ ọdun mẹdogun si aiye k i o t o ku

## Awon Olosa Gbogun Ti Ile-Epo Moto Kan Ni Ilu Onitsha

ONITSHA-Ni ọsẹ to kọja ni awọn janduku ọlọṣa pẹlu ihamọra ohun ọsẹ bi ibọn, ada ati ọgọ lọwọ wọn, ni a gbọ pe nwọn gbogun ti ile epo mọto kan ti o wa ni opopo New Market ni ilu Onitsha.

Larin pe nwọn ngbogun ti ile epo na lọwọ bẹni nwọn tun gbidanwo lati fi jamba ṣe mọto akero kan pẹlu ọpọ ẹru ninu rẹ ti iye owo rẹ jẹ ẹdẹgbarun pọnun (£900) ati lati ko gbogbo ẹru inu rẹ pata.

Atukọ (driver) ti o nwa mọto rẹ sinu gbangba ile-iṣẹ awọn elepo mọto na ni ireti ati ja awọn ẹru inu rẹ silẹ ninu ọja Onitsha ni owurọ ọjọ keji, nitori oru ti ru pupọ ki o to de ilu Oniisha.

pe ọlọṣa ni ni nwọn, nigba ti awọn ọlọṣa wọnyi de idi mọto na, nwọn ṣebi kosi enia nibẹ ni, ṣugbọn ireti wọn ṣaki nigbati gbogbo awọn ero inu mọto na doju ija kọ wọn lojiji, ojo si dẹ ba wọn.

Irohin ti o de si eti igbọ wa lati ilu. Onitsha t u n nfi ye wa pe, nigbati awọn ọlọṣa na de, ti nwọn rọlu ile epo na, nwọn ba bẹrẹsi yin ibọn si mọto akero na, nwọn si fi ọta ibọn fọ ẹsẹ rẹ mejeji ti o wa niwaju.

Gbogbo awọn ero inu mọto na ni nwọn farapamọ ni gbara ti nwọn ti mọ

Nwọn fi ẹsẹ fẹẹ, ṣgubọn ọ an ninu wọn ti ori rẹ tako ni nwọn mu, nwọn si mulọ si ọgba awọn ọlọpa nibiti nwọn gbe fisi itimọle Ki o to di wipe o wọ itimọle, awọn ọlọpa yẹ gbogbo ara rẹ wo, nwọn si ba awọn ohun ọ ṣ ẹ ati ibọn kekere kan lara rẹ.

# ELETI-OFE

(A NJU WỌN KO ṢE WI LẸJỌ)

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLE & TELEGRAMME

28, Kosoko Street, Lagos, "ELETI-OFẸ" LAGOS

P. O. Box 467 Phone 23370

VOL XIV NO 930 SATURDAY July 18 — July 24 1964


Oro Olotu:

# Oba Adele Keji

Bi awa onirohin "ELETI-OFẸ ti bẹrẹsi kọ nkan ti a ri, ti a gbọ ati eyiti a mọ nipa awọn Ọba Eko ati Ọba Adele Keji t'o waja ninu ọsẹ yi.

O tile yẹ ki ẹ gbọ nkan ti ọkan ninu awọn ọkawe wa, Ọgbẹni Shoyinka sọ ni ede arofọ nipa Ọba Adele na. Ọrọ arofọ na niyi ẹ ba wa ka, ki ẹ si ma gbadun:

## Musulumi Oba Lo!

Iku ko gb'ogun ara
Bẹ ẹ na ni iku
K'o m'eni akii pa
Iba ṣe pe Iku
Mẹni ọwọ ni
T'o si me'ai aipa ni
Ki ba ti pa
Ọba Alaiyeluwa
Musẹndiku Adele Keji
Ọba Eko
Hal ẹja nla lọ
Ninu Okun
Isalẹ Odo
Ru gudugudu
Erin wo
Ni Oke Amilala
Jinijini
B'ẹran o alẹnia
Tade Ọba Adele
Ni Ile Aiye
Lojọ kejila
Oṣu eje
Ọdun 1964
Wọ t'ọmọde t'agba
Eko lati ṣinṣinṣin
Eko donkodo
Pe Ọba rere lọ.
Gẹgẹ bi ẹda
T'a fẹ ni mọ
B'Ọba Adele
Ti ṣ'enis o
Ni o ni alebu tirẹ
Mo fẹ ki ẹ mọ dajupe
Ko sẹ ni
To le tẹ aiye lọrun
Baba ṣe iwọn to le ṣe
Oluwa ko
Pa aṣiṣe
Ọba Adele rẹ
Ko gbe safẹfẹ rere.
Ẹnyin Musulumi Eko
Ẹku asehinde
Ẹku amumọra
T'Ọba Adele
T'owaju
T'ọmọde t'agba 'Eko
Ẹ ku iroju
F'Ọba rere to waja
Gbogbo ẹnyin Ọba Alade
Ẹ ku a fẹ ku
Ọba rere to lọ
Edumare Ọba Ọlọla
Ko gb'ọba wa
Si Ile Ogo.
Gbadebọ Adele
Ọmọ Ọba ti fasẹ muti
Opomulero mọja lekan
Itọ u ile dọwọ rẹ o
T'oripa bi ina ba ku
Nṣe ni i feru bo ju
Bi ọgẹdẹ ba ku
Ọmọ rẹ ni i fi rọ po
Kabiyesi Adele
Wẹ, o yan kanrinkan
Ni o ṣe fi yin
Rọ po are rẹ
Ẹnu rẹ yio daru
Adọrin Ọdun
Ni ọjọ aiye wa
Gẹgẹbi iwe mimọ ti wi
(Wo yoku loju ewe kejọ)

# Iwe Si Olotu

# Awon Ara Sudani Kan Ko Agbako Lowo Ijoba Eko

EKO—Irohin kan de si eti igbọ wa lati ịgboro Eko laipẹ yi wipe awọn ara ịlu Sudanị mẹfa kan ti nwọn sa lati ilu wọn wa si ịlẹ Naịjịra ninu oṣu to kọja fun abo ni nwọn tị da pada si ilu wọn ni ọjọ kọkanla oṣu yi.

Dịdapada yi faramọ aṣẹ ti o ti kotu kekere kan wa ni Eko, ni ịjịroro pẹlu Minista ti nṣe olotu nipa ohun ti nṣẹlẹ lati ilu okere wa, fun ịjọba Apapọ.

Awọn mẹfẹfa yị ti nwọn pe ara wọn ni ẹṣiwaju ẹgbẹ kan tị nwọn npe n (Pan Af can Liberation Movement) ni ịlu Sudan ni nwọn fi ọkọ ofurufu kan ti o nlọsi ilu Khartoum ati Ethiopia gbe pada si ịlu wọn lati ibudo ọkọ ofurufu ni Ikẹja nị alẹ ọjọ abamẹta to kọja.

A gbọ pe awọn ọlọpa ni ilu ipinlẹ Ila Orun ni nwọn mu wọn fun ẹṣẹ wịpe nwọn wọ ilẹ Naịjịria laịnị iwe aṣẹ lọwọ ti o jịnị korokoro, ati pe nwọn sị kọ lati fi ara wọn han fun aṣoju ịjọba ilẹ wọn ti o wa ni ilẹ Naịjịa ni Eko.

Ngbati awọn oniwe irohin fi ẹrọ gbohun-gbohun ba alakoso ile iṣẹ ọkọ ofurufu ni Ikẹja sọrọ ni ọjọ na lati ṣe gbolohun alaye diẹ lori ọrọ na, o dahun pe "Emi ko wa ni ipo ẹtọ lati ni ọrọ kan pẹlu oniwe irohin kankan tabi ẹnịkẹnị lori iru ọrọ bayi.

THE CARELESS OMOLANKE AND IMPATIENT ...



# Awon Egbe Onibu-redi Binu Lori Ekunwo Fulawa

EKO — Laipe yi ni awon omo egbe Oniburedi iyefun, onibuředi dindin ati awon ti nta buredi aladun orişirişi jake jado igboro ilu Eko se ipade ajumose kan ninu eyiti nwon pinnu lati kesi ijoba apapose lati se iwadi kikun lori ekunwo ti ijoba se lori apo iyefun fulawa laipe yi nitori idabobo ati ilosiwaju awon ile ise oniburedi.

N ogunjo osu kefa odun yi, awon alakoso ile ero ti nse yefun ni Apapa so fun gbogbo awon ase buredi ta wipe ohun ti o bere lati ojo kejilelogun osu kefa odun yi, onikaluku onibara awon ti o ba fe ra apo iyefun lodo awon ni awon yio je k o ni anfani l a t i ni adota apo lekansoso eyiti o je eru mo io kansoso pelu ekunwo lati sile metaleladota si sile marundinlogota apo kokan.

Ninu ipade kekere kan pelu awon oni e irohin ni Eko l'ose to koja Ogbeni J. Ade Tuyo ti o je baba egbe awon oniburedi ni ilu Eko sope eto titun pe ki onikaluku onibara ma gba adota apo iyefun tire fun-rare ati fifi sile meji kun owo apo iyefun kokan je ero kan lati fo egbe oni

Ogbeni Tuyo tun ni Isesi awon alakoso ile ero oniyefun je nkan kan ti nwon gbero ni sise lati so ekunwo oja di nkan tipatipa eyiti yio se iranlowo fun idagbasoke owo nkan ije ni ilu.

Awon egbe oniburedi ni ile ise oniyefun buredi yi nikan ni ile Najiria ni o je eyiti ko ni aban di je miran ni ilu miran ni ilu yi ati pe bi nkan yi ba mba bayi lo titi lai ni iyorisi kan, be na ni ede ko yede yi na yio wa titi lailopin.

E ma polowo oja yin, ki e si tun ma ka iwe irohin

ELETI — OFE

ti o kun fun irohin aladun losose.

# Ile – Eko Giga Ti King's College Jagunmolu

EKO — Ojo ayo nla pataki ni Ojo Bo ti o je ojo kesan osu yi je fun awon ile eko ti Kings College ni ilu Eko nigbati nwon jagun molu ninu ere idije bolu gbigba ti nwon gba pelu ile iwe mala ti awon Ahmadiya ti o wa ni Agege lori papa nla ere bolu ilu Eko, ti nwon si gba ife idije na titi ayo. (ZARD CUP)

Iye awon enia ti nwon wa woran ni ojo na pelu awon omo ilewe miran ati ogunlogo awon ti nwon nife si ere bolu to egbedogun enia (5,000).

Totun-tosi awon ile iwe wonyi ni awon ja fitafita



bi akoni lori papa lojo na sugbon awon omo ile King's College faake kori nwon kolu awon aban dije ti Ahamadiya bi igbi omi okun, nwon si mu won padanu ere ije bolu na. Ko si eniti o padanu owo ie fun wiworan alarenren yi.

Eleti - Ofe Daraba

# Lynn Oyinbo Olopanu Fise Sile

EKO—Oyịnbo ọlọpanu kan J o h n Lynn tị a bẹrẹsi gbọ okịki orukọ rẹ nịgbatị nwọn nṣe iwadị ẹjọ awọn Olo͏ye Ọbafẹmi Awolowo, olori a w ọ n ọ m ọ ẹgbẹ Afẹnifẹre (A G), ni a gbọ wipe o ti kọ ịwe fun ọga gbogbo awọn ọlọpa ile Nigeria wipe on ko ṣe Ọlọpanu mọ.

Ẹni ọdun mẹrndinladọta Oyịnbo ọlọpanu na o si ti ṣe ọdun merinla ghako ninu iṣẹ ọlọpa ni arin wa nị ịle yị. A gbọ w ị p e Ikẹja ni nwọn kọ ju Oyinbo na si ni gbara ti o wọ lẹ yi fun iṣẹ ọlọp, o sị ṣe igba diẹ nibẹ.

Tẹlẹ'ẹ'ẹ iṣẹ Ọ'ọpa o d e ni o kọ nṣe ni ilu Oyịnbo ti o gbe ti wa k o t o wa wọ ịṣẹ nịle yi:

Irohin w i p e Oyịnbo Ọlọpanu na fẹ fi ịṣẹ sile ko' ba awọn ara ilu ni ojiji nitorịpe awọn oniwe irohin kan ti fi igba kan gbe ọrọ na si ita ṣugbọn ịgbatị yio wọkọ gba ilu rẹ lọ nị nwọn ko tị sọ fun wa rara.


BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!

Fun ina dídá ati fun imọlẹ

BP SUPERLITE KEROSINE

L'ayo!



Ti o ba ṣe pe Kerosine lo fẹ BP Superlite l'ayo o le ti ṣe nibikibi, ko si wọn, o mọ daradara, owun le ti dara ju fun onje-sise, iná-titàn ati lati mọ ti yínà Kerosine ti oti dara to BP Superlite

BP ju gbogbo wọn lọ!

BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL! · BP PASS ALL!


# Ogunlogo Awon Osise Ile Onisowo Kan Gba Iwe Idaduro Ni Ilu Enugu

ENUGU —Ọkan nịnu awọn ile-iṣẹ nla awọn onịṣowo ti o wa ni ịpinlẹ Iha Ila Orun nibiti nwọn gbe nṣe irin tutu (Nịgersteel Industry) tị o wa ni ibịkan ti nwọn npe nị Emene nitosi ilu Enugu ni nwọn tị gbogbo ịlẹkun ịle-iṣẹ wọn pa ni ọjọ keje oṣu yị, nwọn si tị ha ọgọsan ninu awọn oṣiṣẹ wọn ni ịwe idaduro lẹnu ịṣẹ.

Ninu irohin ti a gbọ latị ịlu Enugu, nwọn sọpe ohun ti o fa idaduro yi ni pe gbogbo awọn oṣịṣẹ na nị nwọn kọ lati ṣiṣẹ, nwọn sị tọwọ lọ ba alakoso ile-iṣẹ na, Ọgbẹni F. Cop'ey ninu ẹfisi rẹ lati bi'ere idi rẹ ti ile iṣẹ na fi kọ latị san owo iṣẹ wọn fun wọn eyitị o jẹ ti oṣu kẹfa ọdun yi ni ẹkun ịẹrẹ.

Irohịn na tun fi nye wa pe tẹ'ẹtẹlẹ ri awọn oṣịṣẹ na t pinnu lati daṣẹsilẹ, bi owo oṣu wọn ko ba pe perepe pẹlu iye ọjọ ti awọn ko fi si lẹnu iṣẹ ni asiko ti gbogbo awọn oṣiṣẹ daṣesilẹ, kakakịrị agbaiye eyitị o kọja lọ laịpẹ yi.

Nikẹhin awọn alaṣẹ ile iṣẹ na tị paṣẹ pe wọn ko gbọdọ daṣẹsịlẹ bi bẹkọ wọn yịo faramọ ohun ti o ba tị ịdi rẹ yọ ṣugbọn ni ṣịṣe aigbọran si aṣẹ yị awọn oṣịṣẹ na daṣẹsilẹ dandan ni ọjọ keje oṣu yi.

L'ọsan ọjọ na awọn a'aṣẹ ile iṣẹ na kọ ịwe idaduro jade eyi ti nwọn fifun onikaluku wọn, lẹhin na ninwọn ba ranṣẹ pe awọn Ọlọpa adịgboluja (Anti-riot police) lati le awọn oṣiṣẹ na kuro nịnu ọgba ile iṣẹ wọn.

Alakoso ile iṣẹ na Ọgbẹni Copley sọfun oniwe irohin wa kan pe diẹ ninu awọn oṣịṣẹ na ni on tị daduro ṣugbọn ẹnikẹni ninu wọn ti o ba wu lati pada sẹnu iṣẹ latị lọ kọ ịwe iwaṣẹ titun si on larin wakatị mẹrinlelogun si ọjọ t i nwọn gba idaduro lẹnu iṣẹ.

# Oro Awon Olopa Aba Di Kotu Ganran

ABA — Ọrọ awọn Ọlọpa Aba meji Damian Iberi ati Raphael Ude ti awọn ọlọpa ẹgbẹ wọn fi ẹjọ wọn sun wịpe nwọn lu ọkunrin kan pa ti dị ẹjọ ti nwọn ni lati gbe lọ si kotu ganran fun ayẹwo.

Gẹgẹbị ẹ j ọ tị awọn ọlọpa wọn ọlọpa ro nị iwaju adajọ kekere t i o nị ki nwọn lọ mu Ọgbẹni alagbafọ kan ti orukọ rẹ njẹ Ukonu Egbuta wa si tensan fun ẹsun kan tị nwọn wa fi sun.

Nwọn ni nịgbati nwon de ile odọ alagbafọ na nibiti o ngbe ni Opopo Kamẹrun l'Aba nwọn fi logun nwọn fi lọgbọn ṣugbọn ọkunrin alagbafọ na kọ lati ba wọn lọ, eleyi lo mu ki awọn ọlọpa mejeji arufin yi ko ponpo ọwọ wọn boo, nwọn lu u ni alubolẹ tịti ti fi pọka iku.

Nị ọjọ kanna ni alagbafọ na ku.

# Nigerian Prime Minister Lunches With Mr. Sanday

LONDON — The Prime Minister of Nigeria Alhaji Sir Abubakar Tafawa Balewa was the luncheon guest of the Commonwealth Relations Secretary Mr Duncan Sandys at his home in West Minister yesterday

The Prime Minister drove there following the morning session of the Commonwealth Prime Ministers' Conference at which the second item on the agenda the progress of British terriotories towards independence and membership of the Common wealth was Continued and concluded

# English For Seafarers

The latest addition to the repertoire of gramophone courses based on the BBC's English by Radio lessons is 'Seafaring in English'. It consists of a textbook published by Gyldenal Norsk Forlag of Oslo and two 10-inch LP disks. The course is a comprehensive guide to the terminology and practice of mercantile seafaring in the guise of a voyage from Tilbury to Bombay of a fictitious but typical merchant vessel, the S. S. 'Pastoria'.

Twenty-two English by Radio gramophone courses have been issued to date. In 1963 some 50 000 courses and over half a million textbooks were sold to private individuals, educational institutions, industrial organisation government departments and other bodies.

# Queen Elizabeth To Visit The Sudan

LONDON — The Queen and Prince Philip are to pay a State visit to the Sudan in February 1965

The Statement from Buckingham Palace yesterday said: 'The Queen and the Duke of Edinburgh have accepted with much pleasure an invitation from the president of the Republic of the Sudan to pay a State visit to Khartoum from February 8 to February 12 1965

The invitation was extended during the President's State visit to Britian from from May 26 to June 4 this year

The Queen and Prince Philip will go to Khartoum at the end of the previously annouced State to visit Ethiopia from February 1 to February 8



## ỌRỌ OLOTU:

# Oba Adele Keji

(O bẹrẹ loja ewe kẹta)

L'ọdun kan le
Iye ọdun
T'Oluwa sọ
Ibukun nla
Ha kọ ni eyi bi?
Torlpe ... ko
Gbeni laipẹ ọjọ
Hal ẹjola bo fọ
Musendiku Adele
Ọba ana
Sawo rẹiẹ Bomi-
ran
O darinnako
Odoju ala
Odi karin ni...
Lokere Firi
Kojọ ni
Baba Kabiyesi
To ba uọruo
Majẹ ọkun
Majẹkoro
Dakno maṣe
K'ọle Onimọ
B'odọrun
Ohun ti
nwọn ba njẹ
Lajule Ọrun
ni ko ma a
Ba wọn jẹ.

x x x x x

Ma ṣe gbagbe
Lati ya ki
Ọlọla Ologbe
Adeyẹmọ Alakija
T ipade ba mbẹ
l'ọruu
J.sẹ wa fun pe
Ilu Eko utẹle
Ipasẹ rẹre
To fi sile o
Awọn Baba wa
Nii maa pa
Lowe pe
" Aje ki gbagbe
Olere, Aguntan
ki gbagbe eleri
bọrọbọrọ "
Ohun ti Ologbe
Alakija se f' Eko
At'ọba Adele
Ni uje baun

xxxxxx

Ba wa ki
Herbert Macaulay
Ejọ́gbọro
Ọkan ninu awọn
oṣe u Eko
T'o b'o gun oṣelu
lọ sọ fun pe
T'ọmọde t'agba
Eko lo uṣe iranti
rẹ o

xxxxxx

Ki a to r'erin
Odi gbo rere
Ka to r'efon
O dọ dan
Ka to r'eiyẹ Bi
ọ kin Od'orun
alakeji
K'eko to tun le
R'Ọba bi Adele
Ọjọ yio ta si
Sunre! Sunre!!
Sunre!!!
Oba ariwajoye.

—o—o—





Our tradition is based on principles of lasting validity: Quality in every detail, true craftsmanship applied to most advanced production methods, safety and elegant styling. The scrupulous application of these principles in the design and manufacture of all Mercedes-Benz products is manifest in the product's performance and beauty. Mercedes-Benz vehicles of today are the embodiment of a 75-year tradition of progressive development in every sphere of car design and production.



MERCEDES-BENZ

DON'T FORGET THAT YOU CAN ALSO TRADE IN YOUR OLD MERCEDES-BENZ OR RENAULT CAR!

LEVENTIS MOTORS LTD.

LAGOS, APAPA & EBUTE-METTA, IBADAN, KADUNA, KANO, JOS, ENUGU, ONITSHA, PORT-HARCOURT & ABA.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosoko Street, Lagos Phone 23370; Editor, (Olotu) Ọla Ọnatade 15, Kosọkọ Street, Lagos, P O 467, Lagos.